**STRONG TOWER ACADEMY**

**IṢẸ́ :Ẹ̀KỌ́ ÈDÈ – YORÙBÁ.**

**KÍLÁSÌ: J.S.S. 1**

**OLÙKỌ́: AYA AJAYI**

Ọ̀SẸ̀: KẸTA

ORÍ - Ọ̀RỌ̀: Lẹ́tà Àìgbẹ̀fẹ́ (Formal Letter)

KÓKÓ-IṢẸ́:

Lẹ́tà Àìgbẹ̀fẹ́ (Formal Letter) ni lẹ́tà sí ènìyàn tó wà ní ipò pàtàkì lẹ́nu iṣẹ́ bíi: ọ̀gá ilé-iṣẹ́ ìjọba, ọ̀gá ilé-ìwé, tàbí lẹ́ta ìwáṣẹ́ abbl.

**ÌGBÉSẸ̀ LẸ́TÀ ÀIGBẸFẸ́**

**1. Àdírẹ̀si Àkọlẹ́tà àti ti ẹni tí a kọ́ sí B.A**

35, Greek Road,

Apápá,

Lagos.

15/4/2020.

ii. Ìkíni ìbẹ̀rẹ̀:

Olóòtu, Ọ̀gá Àgbà,

iii. Àkọlé: **ÌPÈ SÍ ARÉ BỌ́Ọ́LÙ ỌLỌ́RẸ̀Ẹ́-SỌ́RẸ̀Ẹ́**

iv. Ìkíni Ìparí àti àmì ifọwọsí.

Ọwọ́ ọ̀tún ni a n kọ́ọ́sí ní ìpari.

Èmi ni, Tiyín ní tòótọ́,

Òjo Olúrántí.

Àyè kò sí fún àpárá tàbí ẹ̀fẹ̀ nínú irú lẹ́tà báyìí. Èdè tó yanjú ní a ń lò.

**ÌGBÀ KEJÌ( 2nd Period)**

**KÍLÁSÌ: J. S.S. 1.**

**ORÍ-Ọ̀RỌ̀: Àwọn ohun èlo oníruurú iṣẹ́ Àgbẹ̀.**

Àwọn ohun èlò oníruurú iṣẹ́ àgbẹ̀ (Ni ayé àtijọ́). Àwọn Alágbẹ̀dẹ ni wọ́n n rọ púpọ nínú awọn nǹkan èlò wọnyí. Lára àwọn ohun èlò iṣẹ́ àgbẹ̀ ni:

1. Ọkọ́: Èyí ni a fi n kọ ile/ebè tàbí tàbi roko.

2. Ààke: Èyi ni a fi ń gé igi.

3. Àdá: Èyí ni a fi ń ro oko àti gé igi.

4. Ọ̀bẹ: Èyí ni a fi ń gé èébù iṣu tí a fẹ́ gbìn.

5. Akọ́rọ́-Ìkákòkó: Èyí ni akọ́rọ́ tí a fi ń ká kòkó tàbí láti fí /ká àwọn nǹkan tó wà lókè tí ọwọ́ wa kò tó.

6. Apẹ̀rẹ̀: Èyí ni àwọn àgbẹ̀ fí n kó ẹrù ní oko. Àwọn ẹrù bíi kòkó, iṣu àti erè oko.

7. Akòó: Èyí ni igi kékeré tí a fi n wọ kòkó jáde nínú pádi.

8. Àdá ìpákòkó: Èyí ni àdá kékeré tí a fi ń pa kòkó. Kí a sì wọ̀ọ́ jáde.

9. Idòjé: Èyí ni akọ́rọ́ tí a fi n já/gé erè oko.

Gbogbo àwọn ohun èlo wọ̀nyí ní àwọn àgbẹ̀ ń lò láti fi ṣiṣẹ́ oko.

**STRONG TOWER ACADEMY.**

**KÍLÁSÌ: J.S.S. 1**

**OLUKỌ́: AYA AJAYI**

IṢẸ́-ÀMÚRELÉ: (Assignment)

1. Dárúkọ àwọn oríṣìí ohun èlò iṣẹ́ Àgbẹ̀ ní ayé àtijọ́ Márùn-un. Ki o sì sọ ìwúlò ọ̀kọ̀ọ̀kan wọn...